# IPE SI IKORE

**Matteu 28:18-20; 9:38**

**ẸKỌ 365 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹ gbé oju nyin soke, ki ẹ si wo oko; nitoriti nwọn ti funfun fun ikoré na" (Johannu 4:35).**

**"Jesu fẹran awọn ọmọde,**
**Oun ni olutọju gbogbo awọn ọmọde;**
**Pupa ati ofefe, dudu ati funfun,**
**Gbogbo wọn ṣọwọn loju Rẹ̀:**
**Jesu fẹran awọn ọmọde nibigbogbo."**

Awa ti a n lọ si Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ-Isinmi ni ọjọọjọ Ọsẹ le ṣalai mọ̀ pe ẹgbẹẹgbẹrun aimoye awọn ọmọde ni o wà kaakiri ayé ti wọn kò i ti gbọ́ nipa Jesu ri. Kò si Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi ti wọn le lọ, kò si ẹni ti o ti i sọ fun wọn pe Jesu kú lati gba awọn ẹlẹṣẹ là ati pe Oun n fẹ ki wọn ba Oun gbé ni Ọrun. Wọn wà ninu òkunkun, wọn n duro de ki Imọlẹ Ihinrere tàn sori wọn. Ọpọlọpọ ni yoo kú ti yoo si ṣegbe. Awa o ha ti ṣe le duro niwaju Ọlọrun lailẹbi, bi a ba kuna lati sọ fun wọn nipa Jesu!

Nigba ti O ku sáà diẹ ki Jesu lọ si Ọrun, O pe awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ jọ O si sọ iṣẹ ti wọn o ṣe fun wọn. "Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, ki ẹ si ma baptisi wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́: ki ẹ ma kọ́ wọn lati ma kiyesi ohun gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin: ẹ si kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye" (Matteu 28:19, 20).

Ọpọlọpọ awọn ajihinrere ni o ti lọ si ilẹ ajeji lati sọ fun awọn ti kò ni imọ otitọ nipa Jesu, bẹẹni a si ti túmọ iwe-itankalẹ Ihinrere si ọ̀pọlọpọ ède a si n fi wọn ranṣẹ si ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède agbaye; ṣugbọn a ṣirò rẹ̀ pe bi a ba pin ayé si ọna mẹta apa meji ni kò i ti gbọ́ nipa Jesu. Awa ha n gbiyanju lati pa aṣẹ Jesu mọ́ ti o wi pe, "Ẹ lọ si gbogbo aiye"?

**Agbára fun Iṣẹ**

Nigba ti Jesu paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn duro ni Jerusalẹmu titi a o fi fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ wọn, O wi fun wọn pe wọn o gba agbara lati ṣe ẹlẹri fun Oun "titi de opin ilẹ aiye" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:8). Ohun ti wọn o ri gbà yoo fun wọn ni agbára lati sọ itan Jesu fun ọ̀pọlọpọ eniyan ti o jina rére si Jerusalẹmu.

**Inunibini**

Awọn ipade iyanu ni o tẹle Ọjọ Pẹntekọsti, nigba ti ọgọfa ọmọ-ẹyin gba agbára Ẹmi Mimọ́. Peteru di oniwaasu nla lẹsẹkẹsẹ, ẹgbẹẹdogun (3000) eniyan si yipada ni ọjọ kan. Awọn ọmọ-ẹyin n gbadun itujade Ẹmi Mimọ́ Ọlọrun, laisi aniani gbogbo awọn Onigbagbọ́ ni iba ni inudidun lati duro ni Jerusalẹmu fun ọ̀pọ ibukun si i. Ṣugbọn Jesu wi pe, "lọ."

Awọn ọmọ-ẹyin le ṣalai mọ̀ pe akoko ti to lati lọ, ṣugbọn nigba ti awọn Farisi bẹrẹ si fi awọn eniyan sinu tubu, ti wọn si n pa wọn nigba miiran, nitori pe wọn gba Jesu gbọ́, wọn tukaakiri si ọ̀pọlọpọ ilu ti o yi Jerusalẹmu ká. "Nwọn si jade lọ, nwọn si nwasu nibigbogbo, Oluwa si mba wọn ṣiṣẹ, o si n fi idi ọ̀rọ na kalẹ, nipa àmi ti ntẹle e" (Marku 16:20). Jesu ti sọ pe Oun yoo ba wọn lọ, O si ṣe bẹẹ.

**Ipe si Ilẹ awọn alawọ-funfun**

Lẹyin ti Paulu Apọsteli yipada o lọ si irin-ajo ti itankalẹ Ihinrere nigba mẹta. Ibikibi ti o de ni o n sọ fun awọn eniyan nipa Jesu. Loru ọjọ kan nigba ti o wà ni Troasi, ninu iran o ri ọkunrin Makedonia kan ti n wi pe, "Rekọja wá si Makedonia, ki o si ran wa lọwọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 16:9). Paulu mọ̀ lẹsẹ kan naa pé ipè lati ọdọ Oluwa ni, oun ati awọn oluranlọwọ rẹ̀ kò jafara lati lọ si Makedonia. Eyi ni ibẹrẹ iwaasu Ihinrere ni Ilẹ awọn alawọ funfun.

Ọpọlọpọ eniyan ni a gbala nipasẹ iwaasu wọn, ṣugbọn ki i ṣe gbogbo eniyan ni o gba ohun ti wọn sọ. Awọn miiran kún fun irunu tobẹẹ ti wọn fi Paulu ati Sila sinu tubu, ṣugbọn eyini kò dá iwaasu wọn duro. Ọlọrun ti rán wọn lati lọ waasu fun awọn eniyan ti kò mọ̀ nipa Jesu, wọn si ṣe eyi ti wọn le ṣe lati sọ ti Ihinrere naa, laika iyà ti wọn yoo faradà si.

**Sisẹ́ ara ẹni**

Iyọọda ara-ẹni jẹ́ ẹmi ajihinrere tootọ. O n fẹ lati jiya fun Jesu bi o ba yẹ bẹẹ. Kò beere fun ère ayé kankan. "Lati ri ayọ̀ igbala loju ọkàn kan ti a gbàlà tó fun un ni itẹlọrun fun iṣẹ ti o ṣe." O n fẹ lati fi ile rẹ̀ silẹ pẹlu gbogbo itura rẹ̀, awọn ọrẹ ati awọn ibatan rẹ̀ pẹlu, ki o si lọ si ibi ti Ọlọrun pe e lati lọ.

Ki a to le jẹ́ ajihinrere ti yoo lérè fun Jesu, a nilati ri igbala (eyi ni ni pé ki a dari ẹ̀ṣẹ wa ji wa); ki a si sọ wa di mimọ́ (eyini ni pe ki a di ọlọkàn funfun) nipa isodimimọ́. A nilati fi Ẹmi Mimọ́ wọni gẹgẹ bi awọn ọmọ-ẹyin ti gba agbára yii ni Ọjọ Pẹntekosti ki wọn to jade lọ lati jẹ́ ajihinrere.

Lẹyin eyi ẹni naa nilati ni ifẹ fun ẹmi awọn eniyan, ikaanu fun ọkàn ti o sọnu. Awọn ajihinrere ti o ti jade lọ ti wi bayii pe ifẹ tootọ fun awọn eniyan kò ṣe igbe wọ̀. Eniyan le maa dibọn bi ẹni pe oun fẹran awọn ti o n ṣe iṣẹ-iranṣẹ fún, ṣugbọn awọn eniyan le mọ̀ bi o ba jẹ pe lotitọ lati inu ọkàn rẹ̀ ni o ti n ṣe iṣẹ-iranṣẹ yii nitori pe o fẹran wọn gẹgẹ bi o ti fẹran ẹmi wọn, tabi oun n ṣe e fun idi miiran.

Ajihinrere nilati mọ̀ pe awọn eniyan ti oun n waasu fun jẹ́ ọkunrin, obinrin, ati awọn ọmọde ti Kristi kú fun. Jesu kò fẹ pe ki ẹnikan ni gbogbo agbaye ki o ṣegbe. O fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ lati gbà wa là, O si n fẹ ki awa naa fi ayé wa lelẹ ninu iṣẹ-isin fun awọn ẹlomiran. A bukun wa ki a ba le jẹ́ ibukun fun awọn ẹlomiran. A nilati fẹẹ lati jiya pẹlu awọn ti a n ṣe aayan lati ran lọwọ. Eyii ni kò pọju fun wa lati ṣe.

Jẹsu fi Ile Rẹ̀ Iyanu nibi ti gbogbo awọn angẹli ti n juba Rẹ̀ silẹ, O si wá si ayé lati gbé igbesi ayé irẹlẹ, ki i ṣe ninu aafin pẹlu awọn ọba, tabi ninu ile nla pẹlu awọn ọlọrọ̀, ṣugbọn ninu awọn ile keekeekee pẹlu awọn eniyan ti o n ṣiṣẹ́, awọn apẹja, awọn ti eniyan nla ayé kò kà si. Apẹẹrẹ wa ni i ṣe. O si ti pè wá lati tẹle Oun lẹyin.

**Ọpọlọpọ èdè**

Nigba ti awọn ajihinrere bẹ̀rẹ si lọ si ilẹ awọn keferi ni iwọn ọgọrun-un ọdún tabi jubẹẹ lọ sẹyin, ti wọn ri ọ̀pọlọpọ eniyan ti ède wọn kò i ti ni akọsilẹ wọn kò le ka Bibeli tabi iwe nipa ẹsin igbagbọ́. Ajihinrere naa nilati maa gbé laaarin awọn eniyan naa titi oun yoo fi kọ́ ede wọn tó eyi ti yoo fi le bá wọn sọ̀rọ. Lẹyin eyi yoo gbiyanju akọsilẹ awọn ọ̀rọ naa ki ède naa ba le ṣe kọ silẹ. Lẹyin eyi yoo tumọ Bibeli tabi apakan ninu rẹ̀ si ède ti oun ti ṣe akọsilẹ rẹ̀. Oun nilati tumọ ọ̀rọ Bibeli nigba miiran lati bá agbegbe wọn mu. Fun àpẹẹrẹ, kò si awọn agutan ni ilẹ Iceland. Awọn ara ilẹ̀ yii kò ni mọ itumọ pipe Jesu ni Ọdọ-agutan Ọlọrun. Nitori naa awọn otumọ iṣáaju lo "seali" (orukọ ẹja kan) dipo Ọdọ-agutan. Ọpọlọpọ seali ni o wà ninu omi ti o yi Iceland ká, awọn ara ilẹ naa si le mọ itumọ "Seali Ọlọrun." Lẹyin eyi ajihinrere naa nilati kọ́ awọn eniyan naa lati ka Ọrọ Ọlọrun. Ọràn ti o n gba ọjọ pupọ, ti ki i si yá bọrọ ni; o gba ọpọlọpọ ọdun ti o kun fun akitiyan ẹ̀kọ́ ati ọ̀pọlọpọ adura pẹlu iranwọ Ọlọrun lati mu ki ède kan ṣe e kọ silẹ, ki a si fun awọn eniyan ti o ni ède naa ni Ọrọ Ọlọrun lati kà. Awọn ajihinrere wọn ṣe e nitori pe wọn fẹran ẹmi awọn eniyan, wọn si n fẹ ki wọn mọ̀na iye ainipẹkun. Ọpọlọpọ orilẹ-ède pẹlu oriṣiriṣi ède ni wọn n ka Ọrọ Ọlọrun lode oni nitori ijolootọ awọn ajihinrere akọkọ. A le fi iwe-iroyin Ihinrere ranṣẹ si wọn lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati di Onigbagbọ́ nitori pe ẹnikan ti kọ́ wọn ni iwe-kikà.

Iṣẹ naa n tẹ̀ siwaju. Lati ọdún de ọdún ni a n fi awọn ède titun kún awọn ti o wà tẹlẹ, bẹẹni a si ti tumọ gbogbo Bibeli si igba odin mẹta (197) ède. Ẹgbẹrun o le ọkan-dinlọgọta (1059) ède ni o ni Iwe kan tabi jubẹẹ lọ ninu awọn iwe Bibeli. Ṣugbọn sibẹ a ṣirò rẹ̀ pe ẹẹdẹgbẹsan (1700) ède ni ko i ti ni ọ̀rọ kanṣoṣo ninu Ọrọ Iwe Mimọ́.

Awọn ajihinrere miiran ti ni iwuwo lọkan wọn lati sọ fun awọn keferi nipa Jesu nipa ẹrọ ikọrin. Diẹ ninu awọn aṣoju wọn ti jade lọ si awọn ilu ti o pamọ nibi ti a kò i ti kọ ède wọn silẹ, tabi nibi ti a kò i ti tumọ Bibeli si ède wọn, wọn si ti ri ẹnikan ti o le sọ ède ilẹ naa ti o si tun le sọ eyi ti ajihinrere naa n sọ. Lẹyin eyi yoo tumọ̀ ọ̀rọ iwaasu Ihinrere sinu ẹrọ ti n gba ọ̀rọ silẹ. Lati inu eyi ti a ti maa n ṣe ẹrọ ti o n tun ọ̀rọ ti a ti gbà silẹ sọ ranṣẹ si awọn ti kò i ti gbọ́ Ihinrere ni ède wọn. Awọn ajihinrere miiran a maa gbé ẹrọ ti o n tún ọ̀rọ ti a ti gbà silẹ sọ ti o ṣe gbé rìn lọwọ wọn a si maa fi ẹrọ yii sọ̀rọ Ihinrere ti igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ fun awọn ti o ti sọnu ti wọn kò ni oye yii tẹlẹ ri.

**Ẹmi N Sọrọ**

Ọnakọna ti o wu ki a gbà lati sọ fun awọn eniyan nipa Jesu, Ẹmi Ọlọrun ni lati bá ọkan sọrọ ki ẹni ti o n gbọ́ ọ̀rọ naa ba le ri igbala. Ẹmi Ọlọrun kò wá ogbufọ̀. Ajihinrere kan le maa ba keferi kan ti kò mọwe gbadura, ki ẹni kin-in-ni má tilẹ̀ gbọ́ ède ẹnikeji rara, sibẹ Ẹmi Ọlọrun le so ọkàn wọn pọ tobẹẹ ti wọn yoo fi ni alaafia ti Jesu n fi fun ni nigba ti O bá dariji ẹlẹṣẹ ti o ronupiwada.

**Iṣẹ Ajihinrere Ni Ile**

Iṣẹ ajihinrere ti wa le bẹ̀rẹ lati inu ọgba ile wa. Aladugbo wa le maa reti pe ki ẹnikan wa sọ fun oun nipa Jesu. Yoo ha ti ri bi a ba kuna lati sọ fun un pe Jesu yoo gba a kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, tobẹẹ ti yoo fi ṣegbe si ọrun apaadi? Ẹ jẹ ki gbogbo wa gbadura tọkàntọkàn pe ki Ọlọrun fi ẹnikan hàn wa ti a o sọ fun nipa

Jesu, ki a si pe e wa si ile-isin. Nigba ti a ba ji, ẹ jẹ ki a sọ fun Jesu lati dari wa lọ sọdọ ẹnikan ti o n fẹ igbala ki O si ràn wa lọwọ lati sọ ohun ti o tọ́. Leke gbogbo rẹ̀, ẹ jẹ ki a gbé igbesi-ayé wa lọna ti awọn eniyan yoo fi ri i pe ọmọ Ọlọrun ni awa i ṣe. A jẹ́ aṣoju Ijọba Ọrun. Awa ha n huwà gẹgẹ bi ọmọ-ibilẹ Ọrun?

Awọn ẹlomiran laaarin wa le maa rò pé awọn ṣetan lati lọ si ilẹ ajeji lati fi ayé wọn ṣe iranlọwọ fun awọn ẹlomiran ki wọn ba le ri igbala, ṣugbọn ọ̀na kankan kò ṣi silẹ. Ki ni a le ṣe? A le gbadura fun awọn ti wọn n jade lọ, a si le fi ninu owo wa silẹ lati ṣe iranlọwọ fun wọn, lati fi tẹ Bibeli ati Iwe itankalẹ Ihinrere ni ède miiran. Ọpọlọpọ awọn ọmọde ni wọn ni owo ninu apoti ifi owo pamọ si wọn fun awọn ajihinrere. Wọn fẹran awọn ọmọde ti o wà ni ilẹ miiran nitori pe Jesu fẹran wọn, awọn si n fẹ ràn wọn lọwọ lati ri igbala.

Adura wa nilati jẹ́ atọkanwa pẹlu ọkàn otitọ. Ki Ọlọrun ràn wa lọwọ lati le sọkun lori awọn wọnni ti o sọnu, ki a si bẹ Ọlọrun pe ki o rán ẹnikan lati ràn wọn lọwọ ki Jesu to dé. Jẹ ki a gbadura pẹlu ẹmi aimọ-ti-ara-ẹni-nikan pe, "Emi ni yii, Oluwa; rán mi."

Ọdọmọkunrin kan bẹrẹ si fi itara ṣiṣẹ lati mú ki awọn ọdọ́ iyoku le ni ifẹ si iṣẹ ajihinrere. O gbadura pe, "Emi ni yii, Oluwa rán arabinrin mi." O rò pe iṣẹ ti oun n ṣe ni ile ti ṣe pataki ju eyi ti oun lè fi silẹ lọ. Ṣugbọn kò si ẹnikan ti o le yọọda lati jade lọ lati ṣe iṣẹ ajihinrere yii titi o fi di alẹ ọjọ kan ti oun tikararẹ̀ kigbe pé, "Emi ni yii, Oluwa; rán mi." Lẹyin eyi awọn iyoku tẹle apẹẹrẹ rẹ̀ wọn si yọọda ara wọn lati lọ si ibikibi ti Oluwa ba fẹ lati rán wọn. O duro ti ifi-ara-ẹni-rubọ rẹ̀, nisisiyii o n ṣiṣẹ fun Ọlọrun ni India, o n sọ nipa Jesu fun awọn ọkàn ti o ti sọnu.

**Atete Murasilẹ**

Kò si ẹni ti o kere jù ninu wa lati pese ara wa silẹ fun iṣẹ ajihinrere. Lẹyin ti a ba ti ni iriri Onigbagbọ́ mẹtẹẹta ti a nilati ni, a le maa gbadura pe ki Ọlọrun ràn wa lọwọ lati mọ Ọrọ Rẹ̀ si i, ki O si fun wa ni ọgbọ́n Rẹ̀, ki a ba le ni oye nipa awọn eniyan naa ti a ni iwuwo ọkan fun lati ràn lọwọ. A le kọ́ ẹ̀kọ́ nipa àṣa ati ède ilu naa ti a ni lọkàn pe Ọlọrun n pè wá lati lọ. Ṣugbọn nigbagbogbo a nilati maa gbadura pe ki Ọlọrun ṣamọna wa. Ọpọlọpọ ni ẹ̀kọ́ ti Ọlọrun yoo kọ́ wa bi akoko ti n lọ ati nipa iriri. Bi a ba ti n jọ̀wọ́ ara wa fun Ọlọrun tó, ti a si n jọwọ ara wa fun Un lati ṣe ohunkohun ti O fẹ ki a ṣe, bẹẹni yoo ti yá tó fun Un lati pese wa silẹ fun iṣẹ yii.

"Nitorina ẹ gbadura si Oluwa ikorè ki o le rán awọn alagbaṣe sinu ikorè rẹ̀" (Matteu 9:38).

## AWỌN IBEERE

1. Awọn orilẹ-ède wo ni Jesu rán awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si?
2. Nitori ki ni Jesu ṣe paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati duro ni Jerusalẹmu?
3. Ki ni mú ki awọn ọmọ-ẹyin fi Jerusalẹmu silẹ?
4. Ki ni ipe Makedonia eyi ti Paulu gbọ́?
5. Sọ diẹ ninu awọn amuyẹ ti ajihinrere tootọ nilati ni?
6. Bawo ni ohun ti Jesu fifun wa ti pọ̀ tó?
7. Ọna wo ni pupọ ninu awọn keferi gba fi ri Bibeli?
8. Nibo ni iṣẹ ajihinrere wa ti le bẹrẹ?
9. Bawo ni a ti ṣe le ṣe iṣẹ ajihinrere ni ilé?